# Ronú Lórí Òfin Táwọn Òbí Ẹ Ṣe

Fi ìwé yìí ṣàyẹ̀wò òfin kan táwọn òbí ẹ ṣe, àmọ́ tí ò fi bẹ́ẹ̀ bá ẹ lára mu. Ìwọ àtàwọn òbí ẹ tún lè jọ sọ̀rọ̀ nípa àwọn ohun tó wà nínú ìwé yìí.




## ṢÀYẸ̀WÒ ÒFIN NÁÀ

Kọ òfin táwọn òbí ẹ ṣe, àmọ́ tí ò fi bẹ́ẹ̀ bá ẹ lára mu síbí.

Kí nìdí tí òfin yẹn ò fi tẹ́ ẹ lọ́rùn?

Kí lo rò pé ó mú kí àwọn òbí ẹ ṣe òfin náà?

Ṣé apá kan wà lára òfin náà tó o **lè** fara mọ́?

Ṣé o rò pé ó níbi tí wọn ò ti gba tìẹ rò nínú òfin tí wọ́n ṣe yìí? Tó bá jẹ́ bẹ́ẹ̀ lọ̀rọ̀ rí, apá ibo ni?



www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

Àtúnṣe wo ló máa wù ẹ́ kí wọ́n ṣe sí òfin náà?

______________________________

______________________________

______________________________

**Ká sọ pé o lọ bá àwọn òbí ẹ pé kí wọ́n tún òfin náà ṣe, kí lo rò pé wọ́n máa sọ?**




Kí lo rò pé ó mú kí wọ́n sọ bẹ́ẹ̀?

______________________________

______________________________

______________________________

Kí lo rò pé ó ń jẹ́ àwọn òbí ẹ lọ́kàn tí wọ́n fi ṣe òfin náà?

______________________________

______________________________

______________________________

Kí lo lè máa ṣe táá máa fi wọ́n lọ́kàn balẹ̀ díẹ̀díẹ̀? (Fi sọ́kàn pé ìwà lágbára ju ọ̀rọ̀ ẹnu lọ.)

______________________________

______________________________

______________________________

Ká sọ pé òbí ni ẹ́. Ṣé o máa ṣe irú òfin yẹn fún ọmọ ẹ? Òfin wo lò bá ṣe, kí sì nìdí tí wàá fi ṣe é?

______________________________

______________________________

______________________________



www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

# BÁWO LÀWỌN ÒBÍ Ẹ ṢE FỌKÀN TÁN Ẹ TÓ?

Ohun tó o bá ń ṣe ló máa pinnu báwọn òbí ẹ ṣe máa fọkàn tán ẹ tó. Sọ àwọn ohun kan tó o ti ṣe tó lè ti mú káwọn òbí ẹ **má fi béẹ̀** fọkàn tán ẹ mọ́.

______________________________

______________________________

______________________________

______________________________

______________________________






Sọ àwọn ohun kan tó o ti ṣe káwọn òbí ẹ lè **túbọ̀** fọkàn tán ẹ.

______________________________

______________________________

______________________________

______________________________

______________________________


www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania






**Bíi tẹni tí báǹkì ti fọkàn tán torí ó máa ń dá owó tó yá pa dà lásìkò, ṣé o rò pé àwọn òbí ẹ ti fọkàn tán ẹ tó láti sọ fún wọn pé kí wọ́n tún òfin náà ṣe, àbí o ṣì fẹ́ ní sùúrù díẹ̀?**

**Tó o bá rò pé ó dáa kó o ṣì ní sùúrù díẹ̀ kó o tó sọ fún wọn, kí lo lè máa ṣe kó tó dìgbà yẹn kí wọ́n lè túbọ̀ fọkàn tán ẹ?**



**ÀBÁ:** Tó o bá ti kọ èrò ẹ sínú ìwé yìí tán, o lè fi han àwọn òbí ẹ, kẹ́ ẹ sì jọ sọ̀rọ̀ nípa ohun tó wà níbẹ̀.

Tó o bá ti **ń bá** àwọn òbí ẹ sọ̀rọ̀, má gbàgbé ohun tí Bíbélì sọ pé: “Ìdáhùn kan, nígbà tí ó bá jẹ́ lọ́nà pẹ̀lẹ́, máa ń yí ìhónú padà, ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ tí ń fa ìrora máa ń ru ìbínú sókè.”—Òwe 15:1.

**ṢÉ O MỌ̀ PÉ . . .** Àwọn ohun tó wà nínú ìwé yìí tún lè wúlò tó o bá fẹ́ bá ọ̀gá ẹ sọ̀rọ̀ nípa àwọn òfin tó ṣe lórí iṣẹ́ ẹ?

“Bí ìgbà tó ò ń san gbèsè tó o jẹ báǹkì ni pípa àṣẹ àwọn òbí ẹ mọ́, bó o bá ṣe ń pàṣẹ wọn mọ́ tó ni wọ́n á ṣe máa fọkàn tán ẹ tó.”—Látinú *Awọn Ìbéèrè Tí Awọn Ọ̀dọ́ Ń Béèrè—Awọn Ìdáhùn Tí Ó Gbéṣẹ́,* Apá 2.



www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania